ao wa ewe ewuro ojoo, epo obo, ao gun mo ose dudu, ao mafiwe laro

EYONU AIYE TODAJU
Oloyunbere meta, ikoode meta, ati odidi atare meta, a o jo won papo, a o fi sin gbere yipo orun owo wa mejeji, a o po eyi toku mo ose dudu, a o ma fiwe

EYONU ASINA FUN GBOGBO ENI TONA BADI MON..
Opolo ijokun aye kan ao fi ewe lapa funfun 8 tele ikoko agbe opolo lee pelu atare odidi kan ao da ewe lapa funfun 8 minran bo ao jo..
Ao lo kuna ninu ikoko naa ao fi fo eko mun ninu isasun naa ao walo fo ikoko naa mole lorita meta lobatan lona basi...

EYONU

Okete eledanran nla, biscuit die, oga aye, ewe ola to po die, gbogbo owo, ewe oriji, odindi atare 1, a la okete laya, a fi oga sinue, a ko owo le, biscuit, ewe ola, atare, a ran pada, a ju sinu ape, a wa ko ewe orijin to po le, a jo. A ma fi fo eko laro, epo lale.

EYONU OWO TAWON EYAN FIN FI OWO SANU WA AOSI MARI TAJE SE..

Ako alangba 6 odidi atare 6 esuru pupa lopolopo aojo papo.
Ao mafi schnap loo laro laro

EYONU ASINA...

Ori ako alangba kan ao gun po mon ewe lapa funfun ojoo ati ewe ewuro ojoo aopo mose dudu. aomafi we laro kutu..
odaju gan ni ooo

EYONU AWON AYE.

Ori ejo oka tolase lenu kan, Egbo owu akese,ewe omisinmisin gogoro,ewe omisinmisin pelebe,egbo akerejipon,eyele funfun kan,odidi atare kan,ao jopo ao ma fila oyin ojuda laro lale diedie.

EYONU AWON AYE.

Epo obo lopolopo,Adaripon meta,eyin ororo meta,ewe egele lopolopo odidi atare meta,jijo po,ao ma filo eko tutu loru ganjo.

EYONU AWON AYE.

Ereele ewe ajeobale lopolopo,eso laa pupa,owo aganran(tuntun)marun otooto ,iye kanakana,oromo adie kan,odidi atare gidi kan,jijo ,eko tutu tabi milk alagolo kan tabi oyin ni lilo re ni idaji kutu diedie.

EYONU ASINA TO DAJU GIDI.

Ifun adie to tobi dada,epo obo ,ewe olorungo,ao gun gbogbo re kuna ,ao fose dudu ko,ao ma buwe ni araro.

EYONU AGBA OLOYIN LILA

afara oyin ewe ominsinmisin, ewe oriji, ewe alupaida ao jo po ao lo sugar onikoro kan si
OFORE:aye mi yio dun juti ana lo didun didun ki tan lara oyin didun didun kitan lara ewe oju olongbo oriji loni kii efi ori gbogbo ohun ti moba se jimi alupaida loni ki epa oju buruku da ni odo mi ki eko oju rere simi odaju...

OSE EYONU OSOLE

Eiye kowe kan, oga gbigbe meje, igbin agbonu meta, ewe ewuro ojoo ati ewe sawerepepe ojoo, atare odidi kan, eiyele funfun kan, oga aye kan.

SISERE:- ao gun igbin meteta ye papo mo awon ewe ye, ao ko sibi kan.

Ao wa jo kowe ye ati oga gbigbe meje ye papo mo odidi atare kan.

Ao wa da won papo mo rawon, ao fi ose popo, ao wa da eje eiyele funfun ye si, ao fi po po, ao wa gbe oku eiyele ye te inu ogba olomori, ao ko ose yen le mole, ao wa la ose ye larin dogbandogba, ao fi oga aye ye bo arin ose tala ye, ao wa da pa fun ojo meje, lehin ojo keje, ao mafiwe laro laro.

Ise yi, osise Debi pe ona kona ni owo ati mo wole funwa. Odaju

EYOUN

Omo ayo mejo awo lili kan odindi atare kan ao jo po ao da sinu oyin ao ma la lararo tabi HOT odaju

EYONU GBOGBO AYE

Ewe ilufemika, ewe orijin, ewe akonimora, ewe ooyo ibile, itun, ifa, abeere, oju malu mejeeji, eyo atare 7, Gbogbo awon ewe yen gbudo je tutu. ao gun awon

eroja yi lotooto. ao wa po mose papo. ao ko sinu ike funfun. ao te ori ose yi ni ejiogbe..ao ao wa fi owo eyo tikoluju mejo gun oju odu kookan. ao pe ohun re si ao ma we lararo..

OFORE:- itun loni ki omo araye tunmise loni, ifa loni ki omo araye fami mora loni, ilufemika loni ki omo araye femi toju timu loni, orijin loni ki omo araye fi ori temi jinmi loni. ooyo loni ki omo araye yonu si mi loni, akonimora loni ki omo araye tokunrin, tobinrin o fami mora loni, oju nigbayi lowo ori, agbalagba kiije atare ko tuu nu rara..omo araye e ma se pada lehin mi loni. Idaji ni ao ma we ose yi. ita gbangba lao si ti maa we. odaju!

BI OLE BA JI INKAN WA

Ogun to ole ba ji nkan wa a o wa obi alawe meta 2 a o fi gbadura ki ole ti o ji nkan wa yen da pada atipe ki asiri re ko tu dandan a o wa lo fi obi naa ta awon alagbe lore (ikan fun alagbe okunrin ikan fun alagbe obirin) loba pari odaju pe asiri ole na yoo tu tested work ni o

AKOYA ASETA TODAJU GIDIGAN

Isu gbegbe ,
ori okete Toni irun Lara Dada,
ori ikun toni irun lara Dada

atare to gbajumo kan
ao jopo
ao lo kunna Dada ao ro sinu ato ,
ao wa lo kan aba mo igun yara wa
ao dori ato yi kodo sibe lai di ato yi lenu.
Kaiiii Ogun re abenu gongo ,
etu tio wa ninu ado yi kole danu lailai

LILORE:
Ti aba se akiyesi wipe won sa ise kan abi won gbe ebo (etutu) si iwaju ile wa ,
ao lo gbe ado yi nibiti o wa
ao ta si atelewo wa ao pe ohun re si
ao fi hot lo,
to bajewipe ebo bani
ao da leri ebona , Kai Kai enidan iru nkan bewo orun lala.
OFORE:
bi okete ba bi igba Omo inu aja ile ni tin towon ,
bi ikun ba bi Omo tire inu ajaile nitin toooo,
agbedemeji aiye ohun orun ni gbegbe nyee eyin tire si.
Enitoba Dan iru nkan bai wo Kofi ile saso bora.
Oku leleja nta ooooo

ISEGUN IKORIRA ATI IFERAN

Ao wa ka psalm 150, 71, 7times, sinu omi agbon,ati igo bintu kan pelu awe ojo kan ao wa mix omi agbon ati bintu papo...ao ma kan sinu omi iwe, ati ipara..odaju awon eniyan yoo ma feran wa...ikorira yoo si dagbere fun ooo

ASERI BIBO

EWE ABAMODA 16 AYE OGA KAN SCHNAP 2 AO FI OGA YE SIUN IGO KAN bAO WA KO EWE YE LELORI NIUN IGO NA AO WADA OTI YE SI AO DEPA FUN OJO MEJE LEYIN OJO KEJE AO MAMU NI SHOT KANKA LAROLARO HNMM OWOLOWO NI EGUN NA ASO ALASO NI OGA DABORA

EYONU AWON AGBA

ITANNA AKO IBEPE TI YOPO AO JOMO ODIINDIN ATARE KAN ODI LILA NIUN EPO PUPA ENI TI AFESE FUN NI OMALO JA ITAN YE

Walai ise yi daju,Ogun elepon kan)ESO pandoro,isan agbado ,ao gun po,ao fi ori ko,ao mafi fa epon na wa sile,odaju paa,

OSHOLE TUTU,

Egungun agbari oku okunrin,ose dudu ,ewe ekuya,ewe ekika,ao gun po mo ose dudu,ao ko si inu egungun agbari oku yi,ao mafi we ni agogo kan oru,nl ojo kedogunkedogun, ofo re-ekuya ni pawo3x ekika ni gbaka 3xori gbigbe dide kolo gbo owo NLA wa fun ori tutu loni,owo lati owo okunrin lati owo obinrin ati eni ti momo ati eniti nko mo,ao mafi we ni agogo kan oru.

OGUN ALAKALA

koriko iwaju ile ati eyin kule,botuje pupa tabi funfun,odidi atare kan,ao jopo ao po mose,odi wide,odaju gan.

OGUN ILEYA

irun ori oku odidi atare kan,ori elubu ao jopo aro sinu ado ,,ti abafe lo laro ao pa ofo re si-aridipo ni ti oku,aritagiri ni ejo,titomode tagba bari ejo jinijini amu,terutomo toba rimi loni,ki jinijini mu,ao fi sa ori,walai loba tan.

LATI BORI OTA

ewe ajeobale igi obo igi NLA odidi atare kan,ao jopo,ao po lose dudu,ao ko sinu igba olomori,wiwe ni ekan ni ojo meta, ofo re-ida giri kida igbin,otutu kimu eja ni

sale odo,sango ki gboju ko pa Alakan nisale odo,aki sope inu urun APA,beni aki sope Edo ndun gbin,beni aki sope Edo ndun iroko,beni aki ki ESE ku iroju ana,ojo ti omode ba Dari so igi oruru ni jona ni won nru WO Igbo lo,gbogbo eni ba Dari sami ki won ma ru wo Igbo lo,e t c

OGUN GEGE ORUN

egbo ifon egbo agbesa egbo arunpale,egbo kataba epo amuyun,ewe alupaida,ewe ahara,atare ao gun po,ao mafi aso di mo orun na. 7)Ose ero igbona)egbo ewe abo,ewe ako rere,eru Alamo isu baka alubosa elewe,ao gun won po mo ose,ao ko sinu agolo olomori kan,ao fi omo ayo kan le Lori,ao mafi ose na we. 8)aparun)agbon kan,ose dudu,kaun bilala,ao fi ose yen bo agbon yen patapata,ara re ko gbodo han sita rara,ao lo kaun yio po,ao San mo ara ose yen,ao GBE sinu apadi,ao Jo patapata ,ao da sinu oti,ao ma mu ni gasi kokan,aOgunle sin si orikerike ara ninu re.

OSE AWURE OWO KIAKIA

Ori ere ,ori oka ,eyele funfun meji ,eiye etu kan, ewe rere (201),omi osa, omi okun, ewe gbogbo

nise(awogba arun)(201),iye aluko mewa, iye agbe mewa,owo eran iki osi ,a o gun gbogbo repo mo ose ,a o pa odidi eran kan si lati fi se Sara fun ose yi ,obinrin ko gbodo foju kan ose yi,aso funfun ni a o fi ro idi ta ba fe we ose na ,a o ko ose yi sinu awo funfun olomori, emeji losu ni a o we ose yi ?

IMULE AWAN AGBA

Odidi kowe tope isu esuru pupa oga gbigbe meta eku asinrin meta ako alangba meta abo alangba meta sisere

Aopa epo obo pepe aokole awan eronja toku Lori aofi odidi atare kan si aojopapo aoro sinu sere

Lilore =aomafi ro ekuru funfun je ninu awo funfun ni ojo alamisi

By sheik Daud Arademi

.AWURE EYONU AGBA

Ori aparo, eebu isu ti aparo saje ni oko, orogbo gbigbe topo, iye awon agba, aogunwan po, aora iyo oni silekan iye ni aye atijo, alera iyo abudi oni fivety naira, aobu die ninu iyo ye sinu ohun tiagun ye, alo tio kuna dada, aodasinu oyin origina aomala, iyo tio ku ye aogbodo lo nkankan ninue leyin eyi tiapo mo oogun

ye, aolofise sara fun onibara obinrin, adura wa yio gba o

IMULE AWON AGBA TODAJU

aowa adie dudu ti otipamonri
aodusi inu isaasun tuntun kan
aolu adie yii lati idi aoko ifunre jade aoko owo eyo (16)sinure
aoko eiye ega tako tabo sinure
aomafi ewe ejinrin tutu
aofi yi gbogbo arare tikoni yio ibikankansile aowagbe sinu isaasun naa aojopapo aolokunnan daada aomafi epo pupa lani ale
aofi oti schnapp loni owuro kutu kutu hair,

AGADAGODO TI ANFI NTI PA, MOTOR, EYAN TABI OBINRIN*

ESO bomubomu kan, Ewe rekureku, erupe ile totu die, ODIDI atare kan ekisa ori akitan Ao Jo gbogbo re papo Ao wada sinu owu otutu Ao di ni iko beere mo eyin *AGADAGODO* yen Ako ki owo ti agadagodo yio afiki afiti Ara ogiri tabi ile'le...
Ofo re.....
Akifi tutu bile
Akifi Oran akisa bi akitan awu fohun ni ti bomubomu

Agadagodo muna metu rekureku kifarekoja ona
Ao daruko eniti afeti mo agadagodo yen si enu re tabi number moto ti abamon eni Toni oko na asilefi mu obinrin na

ISASI

Itana Ako ibepe
a o Jo pelu
odindi atare kan a wa lo Ra gbogbo tinu eran ati eje re ao da sinu Awo sobi a o bu eru yen die si ao so fun awon agba wipe eran ifun eje lagbaja le le Yi ki won mu
ao wa awon sobi Miran
a o bu epo di last time ara wa

IMULE AWAN AGBA

Odidi kowe tope
isu esuru pupa
oga gbigbe meta eku asinrin meta ako alangba meta abo alangba meta

*sisere
Aopa epo obo pepe aokole awan eronja toku Lori aofi odidi atare kan si

aojopapo
aoro sinu sere

Lilore
aomafi ro ekuru funfun je ninu awo funfun ni ojo alamisi

EBE/IMULE AWON AGBA TODAJU

Alubosa elewe tutu kopo die
ao gun dada
ao popo ma ose dudu
ao wa eyin adie Oojo
ao do gbon fo lori die ti korofo eyin yi konibaje
ao jo omin eyin yi sinu ose yi
ao tun gun dada
ao wa igba olomori ao ko ose yi si ninu ao wa fi korofo eyin yi gun ose yi lori logan gan ibi ti ati fo eyin na ni yio koju sinu ose,
ao ti koko dogban fowo jin ibibe kato fi eyin na gun ki korofo eyin na maba fo.
Ao ma buwe nigba toba wuwa.
Iseyi daju ijo taba bere wiwe re ojona ni yio bere ise

OSE ANU NLA

ao wa eran elede ekiri kan,
ewe iyalode pupa,ati ike ff olomori.
Aofi ewe iyalode yen tele inu ike nan
ao wa fi eran yen lelori
ao wa tun fi ewe nan bo eran yen tikoni hen awa depa fun 16days,
lehin ojoo yi
aofi ose gana popo ninu ike nan odi wiwe.
odaju

AWURE.

awon ise tansotanso re ooo
ewe kataba oojo
ao lomo eko elewe ao wa pomose
ao kosinu ike funfun wiwe
odara

ASEJE OSHO INU

Ewe Aje sefunsefun
Igbin tobonu 2
Saaru Maitu
Eran lamii basi 3
Ata ijosi 16

Aoge igbinkan si mesan 9,
aolo awon nkan wonyipo tiyiokunna Dada,
aofise Eran lami ati Eran igbin yen lepo niyo,
tabajetan
aomu hot lelori,
aoloso igbin keji si Odo tinsan... Odaju,
baba nsemu hot si laomari owo.
Amon inuwa abere sini tobii.

ASIRI FUN INAWO(PARTY) KIA KIA.....

Eso ooyo,
atare odidi,
ao Jo po,
ao te ni ejiogbe,
ao ra fitila ati owu tuntun,
ao da ebu yi si pelu epo,
ao ma tan ma pe ohunre si bi inawo ba kun die,

OFO RE..
alakotan loruko ti a pe iwo ifa*3,
alakoku loruko ti a pe iwo esu odara*3,
ati kumo lapa awo ni mo seju loruko ti a pe eyin iya mi aje*3,

nibo ni e wa ti ebi pa omo awo,
eyin iya mi osoromoniga e lo ko apo owo wa fun emi
L/L continue

SIRI ASHINA EYONU

Eku asin 3 iga gbigbe 3 opolo gbigbe 3 odidi ataire nla kan ao jo ao dasi inu kegi 2and hair liter ao da shinap igo 2 si ati oyin ilarin ijo si ati milk 2 ao de pa ao mamu gasi kan Lara ro abaramu

ISOYE TODAJU

Ori akuko adie togbo dada, ewe akoko, aofi ori akuko yen tele ape, aoko ewe akoko bo lori mole, aofi odidi atare kan si, aojo aolo Kunna dadaa, aoda sinu oyin aomala ni owuro kutukutu
(2) ewe ogbo mesan, ewe alupaida mesan, odidi oga gbigbe kan, aojo pelu odidi atare kan, aoda sinu oyin aomala ni owuro kutukutu pelu ika arin wa

(3) ewe amunimuye, ewe iyeye, odidi orogbo kan, aolo papo aoda sinu epo pupa aoma laa ni alale ki ato sun

(4) ewe iyeye aolo papo, aofi se ewa je lepo niyo,

sugbon kosi ata nibe, aoseje aoje pelu opolopo adura.

OGUN IGBOYA /IKIYA

Ao wa edun aran, ao fisi ina ti yio pan, ao fi sinu epo tada sinu awo, toba ti tutu, ao la. Lobatan

ASHINA ASIRI BIBO

Eku asin 3 oga gbigbe 3 opolo gbigbe3 ewe tude ati egbo tude odidi ataire 3 ao jo papo ao lo papo ao daasinu kegi 2 and haif liters ao oti shinap tabi Lords ati oyin (honey) idaji igo ao mi papo gasi kan

ATUDE TODAJU

Ewe tude
egbo tude
iyere
ao lo ti yio kuna dada
ao ra isasun tuntun ao fi se odidi igbin kan je lepo niyo lodidi ni
ao se igbin yi o akoni ge ti obajina ao so kale
ao je ko tutu
ao wa bo gbogbo aso orun wa ati oruka
ao wa ni ihoho omoluabi
ao wa da aseje na si ilele ao kunle ti

ao wa ka owo wa mejeji seyin wa
ao wa se adua itusile
ao wa fi enu gbeje lodindi iseyi daju danwo kori botiri
Ike oloun ola oloun komaba alayelorun

NB
ori ilele cement or tiles lamada aseje yi si leyin ti ati nunu dada ao dasi

ao waje

MADARIKAN
Ewe ina pupo,
ewe esinsin pupo, ewe aragba,
ewe oyin,
adie opipi kan,
awun (Ijapa) kan, igbin kan,
ao jo gbogbo re po, ao ro sinu ado kan, ao pa obuko kan si, odi jije.
Ao te ifa iru ekun si.

OFO RE:
Won ranmi lo si igbo erin mode,
won ranmi lodo orisa mo bo,

won ni mo fe obinrin ogboni,
won tun ni mo soro imule lehin,
beni emi ko soro imule lehin,
asewa asehinbo ni won nko ebo ko edi timi,
awon ti nko ebo ko edi timi,
aku doju dele niti igbin,
aku daya dele niti awun,
ojo ti opipi ba se oran aja ni ti owo ti ese re nse,
ilekogba,
ona kogba,
ona orun logba awon ota mi niti ewe aragba,
kankan lewe ina njo omo,
warawara lomode nbo oko esinsin, Omode ni o nfe yinyin,
ona orun ni wa ri yinyin orisa.

ASINA TODAJU

Ao wa itanna sawerepepe ojo topo die pelu ewe amunimuye ati iyare ao.lopo ao se Igbintogbonu nla kan.Ao ge si mefa6 ,ao selepo niyo ao se adura si ao je odaju..

AWEDANU

ewe awede tutu epo obo aidan eyo kan ao gun po ao ko sinu ike funfun ao mawe lalale sun ao mafiwe ninu ajadi apere

OSOLE TOJE

Ao toju ewe ori sare aojo pelu odidi atare kan loto ao lo epo obo loto ao lo igbe adie gbigbe loto so wa papo aopo mo ose ao ko sinu posi iroko ao mafi we e danwo ogun ni

OGUN AWOKA GBOGBO OFA

epo akasan, epo edungben, epo idi, epo oganwo, epo orogbo, egbo agunrun, inabiri, pahoi, kannafuru, aidan, eru alamo, ariwo, kanfo 7, kafura pelebe odidi kan, taba dudu, iseta, etu bon gidi, a ki Gbogbo e lagbo ninu ikoko nla ao fi omi ogi se (omi dun) idi ikoko na ko gbodo kan le mo odi mumu in gasi kookan lemeta lojumo. Baba e je kadan wo mo ti lodada ti Oluwa gba Owo mi ti opolopo enia sile.

ELEYI NI EYONU AWON AGBA TODAMI LOJU OKERE SHUGBON ISE NI .

Ewe Orijin,ewe Mafi Owokan Omo Mi,eqe Ajeobale,ao Fun Po Mo Ose Eyikeyi Ao Ma Fi We Lale Oduju...

OSHOLE

Ori Oka 1, Ori Ere1, Ori Igun 1, Ao Lo Ni Otooto Ao Lo Ata Ijosi 16 Mo, Ao Wa Ra Okan Malu Ako Ti Ko Womi, A Ge Si 16, Ao Fi Se Laseje.

OSHOLE NLA RE O

odidi igun tifuntifun aye ologbo nla kan, eyin ibile 41, ewe ogbo lopolopo, adin igo 2, epo pupa igo 2, Ori abo kan, ikoko tuntun nla meji, a fi ewe tele a ko awon elo yen le a wa fi ewe toku bo loke a o tu adin, epo, si a wa gbe Ori le lori ao jo ko to jo tan ikoko yen leti fo a wa da sinu ikoko keji ao lo ada sinu I go funfun .LILORE:- ago 11pm- 12am, ogere epo pupa la o ma fi lo ninu Awo funfun.

OSE ASHINA AWON AGBA

ewe arojoku a lo ao wa po iyerosu mo ao wa fi te Gbogbo odu IFA merindilogun, ao wo po lose ao ma fiwe. Ogun ni give try. E ma binu Emi Omo kekere na ni Woli Opa e Ku kale mo npadabo.

ASIRI BIBO ASEJE

Ao wa Eran aguntan ao ge si ona 16 ao fi itanna tonnagbowo ati iyere tabi ata ijosi ati epo iyo ao fise je ao fi iru naa si ao se Adura bi asenfe si yio bawa laramu

OGUN STROKE TODAJU

Roro towa ni enu igbado lopolopo ti abafejo ao nije kio di eeru oo ao da sinu hot enina yio mamu osise taara nio Ki awon iya male ba ogun je mowa Lara Ee W Ewe iya ao gun mo ose tio ba wun wa ao mafi we Ajiwo Kanrinkan ti won fi we oku aje olokun nla kan atare odidi kan aojopo ao fi singbere yi orun owo wa mejeji po

OSE AWORO TODAJU

Ewe Efin Rin, Ogiri, Asa Ti Won Ma Mun, Ao Gun Gbogbo Re Papo Pelu Ose ,ao Le Ose Yi Mon Eyin Lekun Inu Le Ao Mabuwe Lararo Kutu Kato Soro Si Eni

Kan Kan, Pelu Gbolohun Re, Firi Firi Ki Won Nile Elefinrin Giri Giri Ki Da Nile Ologiri, Be Fun Mi Ta Fun Mi Ki Won Nile Alasa, Bi Onile Batilekun Dandan Ni Kosi, Eyin Tolaye Esi Lekun Anu, Owo, Ola, Ire Gbogbo Fun Emi Lagbaja Omo Lagbaja Loni

AWORO TODAJU SAKA, TI YIO MAMU AWON CUSTOMER TONI OWO GIDI LOWO WA

Ao wa agbebo Adie dudu toti pamo ri daada, Ao wa isasun olomori totobi daada, ao wa epo pupa igo kan, Adin eyan igo kan, owo eyo tio luju 41, epo obo die, epo igi nla die, obi abata oloju merin 4, ewe rinrin, ewe efo tete abalaye, ewe odun dun, ewe ajeobale, ewe oriji, ao la adie yan laya laaye, ao ko gbogbo awon eronja yi sinu adie yan, ao wa tu epo pupa ati adin yan si, ao se adua oun tia fe koma muwa si, ao wafi omo rire de, ao weni owu dudu ati funfun, ao lori mole ni inu shop wa tabi office wa tabi ile wa.

OSOLE AANU

Oju odindi maalu mejo,gbogbo re yio je merindinlogun,

Orogbo merindinlogun

Obi abata merindinlogun

Gbogbo owo ti anna ninu ilu ti aba ngbe,
Aoko gbogbore sinu isasun pelu odindi atare kan aojo papo ninu isasun tuntun aolo kunna ninu isasun naa.
Aowa bu epo lee lori aotun bu oyin lee lori.
Aola gbogbo re tan.
Ati eniyan ati Alujoonu ni yio maa fi owo bowa lasiri.

Emi koitiri ADINILOWO tole di ASIRI yii lowo.

OSOLE

kahun bilala, Asa imu, a o gun mo ose. A o pensi ona mefa6. Odi wiwe.
Ofore: Elefun, Elegba, O gbagba, tin gba owo ode iluyika, eyin meteta awalogba owo temi Tima na loni wa fun mi, kaun loni kiwoma kanju mu owo wa fun mi, ni kia kia ni warawara, Asa loni tomo de tagba kiwo o sa tile tona won wa fun mi. Emi lagbaja omo..... Loni kio oro temi ti moso loni, koma se lokan omode ati agba kanmo wa fi owo oowo (hand) wun bemi ni ise timo mose loni oo kama mu owo wa fun mi lona kona. Ose loni kose beeni kori.

AROBI/ASETA

A o fi iso tuntun lu oju agbon kan,a o wa ko omo atare 42 si enu a o je kuna,a o mu omi agbon yen si pelu adura pe gbogbo eni toban dimi lowo ise rere ki oro re o dojuru,ti aba mu omi tan,a o fo agbon danu.

OSE AWURE/ITAJA

Ewe ominsinminsin gogoro, ewe abamonda, oga aye kan, ikode 3, ao gun gbogbo re papo ti yio kunna daada, ao fi ose poo, ao wa fi lofinda bintu kan po ose naa, A mafiwe larolaro

MO TI DAN ISE YI WO OSI DAMI LOJU.ASEJES EGBE NLA

eyele ff kan, a lamole yo ku le kan na, atu ye re ati ifu re kuro a wa fi ewe renren ati iyere abi ata ajosi se eyele na lodidi ninu isasun tuntun, a ko gbodo so obe na kuro lori aaro tatise obe yio,

Lilore:- to badi Dede ago meta oru 3:am, ao te aso ff idaji Opa sile a wa so obe yi lelori, a wa se owo bi #50 o ma je mokanla (11) a da sori aso na a wa bo si ihoho a pe

OHUN RE: - Ejilamiri3* Ejilamiree3* Ejilabawun3* Dindin bi owu omo olokun3* seresere lorun ope3*

won ni ta lonpe awon ejilamiri, won ni talo npe awon ejilamiree, won ni talo npe awon ejilahun, won ni ta lope dindi bi owu Omo olokun, won talonpe seresere lorun Ope,mo ni emi LOL ni mo npe yin o, won ni nitori kin mo se npe awon? mo ni nitori nko lowo lowo ni mo se npe yin, Nigbati gundogundo ilekan ko gbodo gundomo, Nigbati logilogi kan kogbodo logo mo, omode kekere kan kogbodo sunkun omu mo, Nigba na ni ki eyin Iya osoronga lo GBE Owo nla nla bi million wa fun emi LOL ao je Pelu Adura.

NB:- a ji ni idaji leyin ta ti je aseje na tan a wa lo pe owo ta ko sori aso tati je aseje na fun awon onibara mokanla, sugbon taba tife lo pin Owo na agbodo mu owo mi dani bi #1000 nitori a ma pade enikan to ma toro Owo lowo wa a fun ni odidi Owo na a wa juwe ile wa fun to ba dojoketa Agba alejo ta gbe Owo gidi wa odaju, sugbon o depend bi a ba se leyoun Lara si.
N. B, 1. ao se ni irole, afile si ori aro da oru ti afije.
2. Ale Saturday mo oru Sunday lagodo se o

ASEJE ASINA TODAJU

Eja aro to tobi, igbo mimu die ati ata ijosi 21 ao loo ata ijosi yen pelu igbo mimu yen po o fii see Eja aro yen ao

fi epo ati iyo sii, ti oba jina tan ko ni kan ile moo, ao fii iyere osun tee ifa ejiogbe sii ao see adura sii ao wa da sinu a see jee yen odidi jije, odaju gan

OSE EYONU AFERO AGBALUKA

Ewe ejinrin tutu tabi gbigbe (Eyikeyi). A o lo kuna.
A o fi ko ose.
A o fi oti die si.
Oyin to po lama a fi po. A ko gbodo fomi si.
A o ko sinu igba olomori kan.
A o maa fi we lararo.
E
Aago meji oru ni a maa n se ose yi.
Ti a ba ti n we e , a o maa wipe......
Gbogbo ewe ati igi OKO ni won Faye gba ejinrin , ki omo araye Faye GBA mi, ki won maa yonu si mi , ki won maa Fola ji mi.. Ki won maa fowo ki mi, ki won maa fire ji mi, ki to mode tagba maa fa mo mi noja Temi.ki won maa yo momi ....Emi ni kin gbale ki n gbona nilu yii. Emi ni kolola maa wa ri towotowo owo won ki won maa wa fowo ji mi, fola jimi, fimoto ji mi, fi le ji mi......]

IFERAN OBINRIN CUSTOMERS OBINRIN

Eleke segi, efun, osu, Eleke tun, Eleke ifa, ao gun po, ao da sinu lofinda. Ao mafi pa oju ati owo, ara.

2. Sperm ati estate kan, ao jopo, afi ebure fun je

3. Ewe ominsinmisin mejije, ewe sekirinmidi, afaimoni konimira, afara oyin, ewe origin, estate kan, ao jopo.

A o mafi oyin lo laaro,

OFORE. Didun didun kiitan Lara oyin, didun didun kiitan lara ominsinmisin, ewe origin loni ki efi gbo nka té emi LOL base jinmi, sekirinmidi afaimoni konimora, ki gbogbo awon olowo ati olola, ati obinrin ati okunrin ki won o mafi owo oowo won ko emi lol

3. Ewe owu Akese tutu, ewe rerinkomi tutu (ewe emiesu) ewe abamoda, ao gun gbo gbo e po, ao fun omi sinu lofinda 6 flower, ao ma fi pa oju ati owo mejeji

4. Ori awawa kan, ewe rerinkomi, abere, eku asin, estate kan, a jo papo, ao pin sin meji, ao po kan lose, ao fi Ikeji si lofinda

5. Egbin abonu kan, eto ekasi, ao fi boo egbin yin, a o yo egbin yen, ao fi estate kokan joo egbin ati ikarahun loototo, a o ma fi si ohunje si enina
N. B. Ebu egbin ti firan, ebu ikarahun ika ife loju

5. Eto ekasi, esu emina, ewe ati agbado fun fun agolo kokan. Ao re gbo gbo e sinu eto fun ijo meta, layin I joke keta, a o jo po. A fun customers je

OSE ASINA

Ewe Akoko toojo 21, eyi ti ko lu rara . A o fi rori sun moju, ti ile ba ti mo dada A o lo po mo taba mimu, A o po mose eyikeyi. A o ma fi we

ITUWO AWON AGBALAGBA

A o gun epo obo mose, A o fi epo pupa po ose naa. A o ko sinu fitila oloju kan, A o ma fi ose naa we ni gbogbo igba

AJEGUN

Egbo lapalapa ati odidi atare ao jopapo ao lo ao ma fi epo pupu la ninu awo ipese

ASEJE OWO

ewe abamoda kan ewe ogbo kan aolo pelu ata ijosi aofise igbin ilako kan je lepo niyo

AWEBI WEPE DANU

Ao lo wa epo obo die ao gun mo ose dudu pelu ewe bomubomu ao lo fi we lodo lekan soso.

BASIRI Mi

Afatan irun ori wa, AO fi bo agbado odindi kan ti omo inu re ko din rara. AO lo rimole ao ma Fi omi fo ori wa si ori ile agbada yi titi yio fi hu sita bi ika owo wa. Ao wa fatu ao gbon gbogbo iyepe idire, ao Jo ao ma Fi foko mu

IPARA ANU

ao wa ewe anu gbigbe,ao lo pelu kafura pelebe,ao lo papo,ao da sinu ipara.... Ao mo fi para

ISE ANU

A o fi oti gbo ewe orijin ati ajeobale a tu milk si odi mimu....

AWORO

ori ako ati abo alangba aojomo odidi atare kan aofi iyo die si aoro sinu ato aosoko inu ile abi shop.aonide lenu

OSHOLE TODAJU

Ori eye osin kon, odidi igbin toba gbonu kan, ewe omisimisi gogoro, ewe ogo, aojopo aolo kunna daada aoma firo ekuru fun fun je laarin oru.

AKO EYONU AWON AJE TI WON YIO FI SEWA LORE

Eye kowe dudu kan eye konakona ti won kola inu re, odidi ejo paramole kan, eye alapandede kan, igbin bonu kan, ogede omimi meji, ewe omisimisi oloju ologbo ao jo gbogbo re papo ao ro sinu sere ao wa pa akuko adie kan fibo sere naa ao le iye igbaya re mo lara ao mafi foko tutu mu ni moday wesday thusday awon aje yio feran wa won yio si matari aje siwa odaju

OGUN OKIKI

Akere Tope, Akuko adie kan, Eye Owiwi 1 ,ori Akuko Ati Ori Owiwi , Ati Akere Ni Ao Lopo Tiyio Kunna Dada Ao Pomo Ose Dudu , Ao Mafiwe Mawi Mawi Nise Eye Owiwi, Owiwi Loni Ki Won Mawimin Kaye Aniyan, Toripe Akere Nijuwe Ibiti Odo Wa Aniyan, Akuko

Nijuwe Ilu Ki Omoaraye Majuwe Mi Si Dada , Odiwiwe .

ISE APASE PAKATI TODAJU.

Ori oka to lase lenu kan, Orogbo ori sango, odidi state kan. A o ji papo, A o po lose dudu, A o pin ose naa si ona meji, A o pin si inu Iwo Igala meji ni kan kan. A o ma fi okan se Adura, A o ma fi okan sepe.
A o fi aso funfun we ti aladura, A o fi aso pupa we ti elepe. A o se aamin(Mark) si. A o ma tola.

Agbara la ko wa, ka to ma wa oro, owo, ola.
Abo oro to fun omoluwabi eniyan.
Eniyan to lowo ti ko ni agbara, asan lo gbe lowo.
Sugbon Oga ni alagbara yii ma je fun olowo, oloro...
Nitoripe Alagbara le fi agbara gba ohun gbogbo tolowo toloro gbojule ni ojo kan soso.

ASEJE BIBO ASIRI

Aoko ko we ose yi na.....
Aowa eso ewe lapalapa funfun kan pelu epo obo die aogun mo ose iwe kan aoni fi omi si oooooo.. Ao Koko we Kia toje aseje yiooooo...

ASEJE NA NIYIOOO

Ewe tanapowo pelu itanna re 16
Ewe abamoda 7 fun obinrin 9 okunrin, Ewe ola die ti koni poju, Ata ijosi 16 ,Ao lopo aowa Lora gbogbo inkan inu malu .. Aowa se lepo niyo.... Aowa so le Ori osuka kan....... Aowa iyere osun aofi te odu ifa IRU EKUN ao wa pe gbolohun re si Bi Omo de ba difa IRU EKUN owo nla nin finko.. Bi agbalagba ba difa IRU EKUN owo nla nin finko... Emi lagbaja Omo lagbaja ti difa IRU EKUN loni owo nla nla Ni kin fiko (aowa daniyan inkan ti aba feran)...
Nitori wipe aba Moda kin daba tie komo se.... Moda ba iye bayi bayi kio todi ojo bayi bayi. Tori oun ti aba Fi dandan wa , dandan Ni Kia ri, ojo ti EKUN bafi IRU kanle ojo naa Ni ase ngun gbogbo oun ti oba fe..
Iyere osun maje ire owo temi sun lodo tokunrin tobinrin loni...Ase
Aowa se adua BIBO ASIRI SI

ASINA

: egbo tude ata ijosin eyo meta epo pupa die ati iyo die. wa lo egbo tude yi kune Dada wa fi ata ijosin yi si wa lo papo wa fi epo pupa die si iyo die si wa wa fi ose ko wa ma pe ohun yi si bi obati fe lo : ojuletente ni sawo

niletetente ise koki se ata komatani lenu iya koki je iyo ki iyo madun lobe atise atiiya koki mu epo kepo maletente lori omi oya esilekun fagba agba fe ronelo esilekun fagba agba fe kole agba fe rale agba fe lowo emi L omo L di agba Loni eyin tolaye oo etumi sile oo eje kin rone Lo wa sadua si wa ma fi we odaju

OSE ASINA

ata ijosi, epo obo, ose dudu, iyo die, ao fi epo pupa si, ao ma fi omi gbigbona we

ASIRI TIA FINLO OGO GBOGBO AWON OKUNRIN TIWON BA NBA IYAWO WA LAJOSEPO

Ao lowa opolo eran obuko oojo, ao lo papo mo #1000 pelu oga aye kan, ao lo oga aye yen naa mo, ao poo mo oori, ao wa kosinu akoto igbin akuju kan totobi daada tia ri he ninu Igbo(koronfo igbin), kosi eniti kole lo nibe, opolopo eniyan lo le loo, Ao mafi pa oko (penis) ba iyawo wa lojosepo, Iyawo wo wa nikan nioo, Edakun ema loo fun eni eleni oooooo.

AWORO ASORO TO DAJU

Ewe iyeye 201,irun iya mopo abo ati ako, akeregbe kekere kan, a ko irun ako ati abo na tale akeregbe na, a o wa ko ewe na le, a o bu iyo topo le, a o wa so si enu ona ile ise wa, ti o ba ti kan sile, ire de o

TURARI ITUWO TO DAJU

Ewe ajekobale, igi oro onigege, epo obo, a o gun po, a o wa sa, ti o ba gbe tan, a o wa ma fi fi turari sile wa ni aro ati ale

IFA ATUDE PEGUNRUN TO MAUN PA GBOGBO EGUN ATI RAN DIRAN RUN LORI TIWA, TALO SO FUN E WIPE WON O KI SE ORIRE NI IDILE TI YIN..

KILODE TI IWO OJE ENI AKOKO TOMA KOKO SE ORIRE NINU IDILE YIN

EGUN IDILE NIKO JEKI OPOLO ONI LARI, OPO LOUN SISE BIA LAE SE., OMO IYA MI GBINYAJU KIO PA EGUN RUN LORI TIE, NITORI AWON OMO TIE TIO BABI KALE, KI AWON NA MABA TUN LO IGBESI AYE INIRA...

Ao wa omunu ewe peregun meta, ao gun pomo Ose dudu........ao wafi iyere osun te ifa ogbe irete, ao wa pe gbolohun re si, ao wapo mo Ose iwe eekan, ao mulosi odo ao lo we Ose na, Ale po Ose yi ko po tia bati fewe lao mabu die die, ao sima pe gbolohun re si Iwo ba tia

bati bu nibe.

OFORE.. Akinmola Ni Elegun Tio Koko Gegun Nile Aye3X,
Elemo Awo Asagede Lo Koko Sa Igede Nile Aye3X,
Ajagunmale Te Awo Atase Lo Koko Ta Ase Nile Aye3
Arugbo Ile Abori Koko3X,
Agbalagba O Gbe Keregbe Lo Odo3X,
Awon maarun ni won pa wopo pa Omo orisa je si oja ejigbo mekun, Orisa gbo o faraya o wole omu ada orisa re.......oun losi ile orunmila,......orunmila ni kilode
Oni Akinmola to Koko gegun nile aye
Oni Oni Elemo Awo asa igede tio koko sa igede nile aye
Oni AJAGUNMALE te Awo atase tio koko ta ase Nile aye
Oni Arugbo ile abori koko
Oni Agbalagba Imule ogbe keregbe lodo
Oni awon mararun ni won pa Omo oun je si oja ejigbo mekun.......Orunmila gba Ada lowo orisa, o mule esu odara lowo,.......Esu odara ati orunmila won nlosi oja ejigbo mekun, Nigbati won de oja ejigbo mekun,
Won ba Akinmola to Koko gegun nile aye, won be Lori, won ni Gbogbo egun enu re ti pare,
Won ba Elemo Awo asa igede tio koko sa igede won be Lori, won ni Gbogbo igede enu re ti pare,
Won ba AJAGUNMALE te Awo atase won be Lori, won

ni Gbogbo Ase enu re ti pare,
Won ba arugbo ile abori koko, won be Lori, won ni Gbogbo agogo enu re ti pare,
Won ba agbalagba Imule o gbe keregbe lodo, won be Lori, won ni Gbogbo, Akadi firaku re ti pare loni yi............EMI OMO ELEHA
epe oso, epe aje, epe lebo loogun, epe babalawo, epe emere, oti pare lori mi Loni yi ooooooo.
Obinrin kan wa ba won nibe, oni haaa emi eyan lepa lopo bayi, Orunmila boju weyin oniki Eje ma jade nidi obinrin na, Eje si bere sini jade ni Idi obinrin na tulututu, obinrin na sare loba oko re, oko re wole o mu apo, o mu oko, o mu orun, odi oja ejigbo mekun,
Nigbati oko obinrin na de oja ejigbo mekun, oba orunmila oni haaa baba Mio mo wipe eyin lewa nibe, bi eku leungba emi o mo, bi eja leun gba emi o mo,
Orunmila ni obinrin re lokoba gbogbo obinrin aye, orunmila ni bi eje yio se maa jade niyi lati ojo kini titidi ojo kaarun, tobadi ojo kefa ki oko re ki oko bo ni idi okunrin ni yio fibi.
Orunmila ni esu odara gbe ori Akinmola to Koko gegun nile aye, won gbe sinu koto kan won wa yerupe bo, won ni ko tun gbodo gegun mo Lae Lae
Won gbe ori ELEMO Awo asa igede sinu koto kan, won

wa yerupe booo won ni kotun gbodo sa igede mo Lae Lae,

Won gbe ori AJAGUNMALE te Awo ata se tio koko ta ase Nile aye sinu koto kan, won wa yerupe bo, won ni kotun gbodo ta ase mo Lae Lae

Won gbe ori Arugbo ile abori koko, sinu koto kan won yerupe bo mole won ni kotun gbodo si agogo enu re mo Lae Lae

Won gbe ori agbalagba Imule o gbe keregbe lodo sinu koto kan, won wa yerupe bo mole, won ni kotun gbodo sa Akadi firaku mo Lae Lae

Orunmila wafi Ada le esu odara lowo, oni wipe kio lo sa igi ona wa, esu odara lekini igikigi lolo sawa, esu odara loni ekeji igikigi lolo sawa......esu odara loni eketa igikigi lolo sawa.........Arunmila gba Ada lowo esu odara

Orunmila losa igi ona wa, o wa risi arin awon mararun, Orunmila ni igi pa epe run lao mape ni peregun,........Odo dun ni peregun daso tie, odo dun ni kiun Mari batise, kiun Rona gbegba, ki ire aye mi kio tomi lowo ni kia kia, ao Se adua si lopo lopo.......ao wabu iwe ekan ninu ose yan, pomo iyere osun tia pe gbolohun si yan, ao lofi we ni odo toun san

AWEBI DANU

epo iroko, epo apa, epo akokirisi, ogede agbagba, a o fi ikan ke ogede na loke, ko gbodo kanle o, a o wa jo po, a o ro sinu ado Kan, a o wa pa akuko adie kan si ado na lara ati iwu adie na lara re, LILORE, A FI FO EKO ELEWE MU LORI ODO NI GBA TI OSUPA BA YO NI A O LO BE

ASIRI BIBO ASEJE

Ao wa Eran aguntan ao ge si ona 16 ao fi itanna tonnagbowo ati iyere tabi ata ijosi ati epo iyo ao fise je ao fi iru naa si ao se Adura bi asenfe si yio bawa laramu

OSE AWORO TODAJU

Ewe Efin Rin, Ogiri, Asa Ti Won Ma Mun, Ao Gun Gbogbo Re Papo Pelu Ose ,ao Le Ose Yi Mon Eyin Lekun Inu Le Ao Mabuwe Lararo Kutu Kato Soro Si Eni Kan Kan, Pelu Gbolohun Re, Firi Firi Ki Won Nile Elefinrin Giri Giri Ki Da Nile Ologiri, Be Fun Mi Ta Fun Mi Ki Won Nile Alasa, Bi Onile Batilekun Dandan Ni Kosi, Eyin Tolaye Esi Lekun Anu, Owo, Ola, Ire Gbogbo Fun Emi Lagbaja Omo Lagbaja Loni

AWORO TODAJU SAKA, TI YIO MAMU AWON

CUSTOMER TONI OWO GIDI LOWO WA

Ao wa agbebo Adie dudu toti pamo ri daada, Ao wa isasun olomori totobi daada, ao wa epo pupa igo kan, Adin eyan igo kan, owo eyo tio luju 41, epo obo die, epo igi nla die, obi abata oloju merin 4, ewe rinrin, ewe efo tete abalaye, ewe odun dun, ewe ajeobale, ewe oriji, ao la adie yan laya laaye, ao ko gbogbo awon eronja yi sinu adie yan, ao wa tu epo pupa ati adin yan si, ao se adua oun tia fe koma muwa si, ao wafi omo rire de, ao weni owu dudu ati funfun, ao lori mole ni inu shop wa tabi office wa tabi ile wa.

ASEJE ASORO ALABOYUN

Ewe aluki die, iyere die, idaro alagbede, ao lo kunna ao fi se aseje eja aro pelu oruko ide kan ati oruka baba kan.To ba jina tan,ao so aseje yin si Ori itedi alaboyun na.odi jije,to ba je tan yio ki oruka na si owo titi di igba ti yio fe bi omo ,yio si yo oruka na

ASEJE AGBE OLA TOJE

Igbin nla 6,ewe osun, ewe ogunmo, ewe sawerepepe, ewe ajesefunsefun,ewe orijin die, iyere die.
Aolo papo,aofi se igbin yanje toba jinna tan, ao fi okuta meta, aokose aroo ninu yara aoso obeyen si ori aroyen...... ?

Iye Agbe 2
Iye Aluko 2
Ikode 2
Iye igun 2
Iye osin 2
Iye akala 2

Aolo papo, aofi tefa(Osetua)aowape ohun resii......

OFORE:

Agbigbo nla eye ifo*3
Eiye ndun makun makun,
Eiye ndun makun makun,
Osefa fun olorii awo,ti oda ajeda oda owo kodami bayiiri ooo'Awerepepe lonii kiwon pemi si ise aje nlanla loni,Osun loniki ire gbogbo koma sunmii bo,oda aje kodami bayiri oo, Ogunmo loniki awon olowo nlanla mafi owo won momii, Oda owo kan kofamiri oo,Orijin loniki tokunrin tobinrin wamafi owo nlanla owo won jinmii lonii, Sawerepepe ki olope ire aje temi wa funmi gbogbo aranii sefunsefun fin sere aje, Agbe kitenii le alaroo, Aluko kite Nile mosun, Odidere kite lawujo iko, Osin loniki ewamafii owo nlanla owoyin sinmii, Nitoripe eiye ti oworegun gegege niwonpe ni igun, ifa jekii oro temii L.........omo........ L, gun gegege nle aiye timowayii, Toripe eiye ti oro re lanii won penii

Akala, ifaje kii oro temii L......... omo........ L la lonii, Tifatifa lanjeran igbin, bi igbin bafenu fale ajifa, kinjifa Lara okunrin ati obinrin, Osetua *3 kiolotu ire aje temii waba mii lonii, Ase niti edumare (ogunyii damiloju ?

OGUN EYONU AYE ATI GBOGBO ENIYAN ODAJU GAN

ao wa ewe ewuro ao lo ti yio kuna ao po mo ose dudu ao ko sinu ike ff olomori ao wa da adi le lori ati epo pupa ati ori leyin na ao wa fi ideri ike na de ti obadi ojo keje odi wiwe

OGUN TANFI WO WERE

Ewe awede tutu, Eja ojiji tutu, igbin apinu mokanla,ewe odundun tutu, aogun awon eweyii Mose ,aofi omi igbin yii poo, aoko sinu ike white aofi fo ori fun were naa, aofi oseyi fori sinu koto, aoju kainkain na sibe aowa yerupe boo..

Eroree.... fun onisegun.

Ewe ipin 201,ewe ero 201,aose laagbo, aofi we leyin ti ati wefun Alamodi yii, aomu die ninu agboyii pelu!!!...odaju

.

GBIGBA ALAISAN SILE

Egbo peregun, odidi atare kan, aobo eepo re, aso egungun,aolo kunna, aopomose ,aola eyele funfun laya, aotun fi aso egungun te ninu, aofi ose yisi aofiwe alaisan naa.. Odaju..

EYONU TI ENU EYAN FI N TENU PADA LAWUJO

Otun wa fun eni to lowo tele ti ko lowo mon.... Ise naa lo bayi. Adan kan, eja abori nla kan, ewe semolapa semolese ti atun mon si ewe papasan. topo, ado ato kan.

...ao gun gbogbo awon nkan wonyipo daada, ao sa ni ategun ti yoo gbe dada, ao lo kunna daada, ao ro sinu ado ato yen, aogbe pamo sinu ile ti ko gbudo kanle mo lailai.

LILO RE....ao ma bu si atelewo wa ni alaale ti aba fe sun, ao ma fi foko mu leyin ti a pe ofo re si tan.

NOTE....ojo mesan ni OKUNRIN yio lo gbogbo re tan sugbon obinrin ojo meje ni yio fi lo tan.

OHUN RE: Akinra awo ori ogbin, olejaa awo ode wuure, biowu awo ode igbarere, edagirigiri eyele aafin, awon mereerin darijo won nba orunmila sota, orunmila pa won, Akinra awo ori ogbin de ode orun odi osho, olejaa awo ode wuure de ode orun odi ogbingbin, biowu awo ode igbare de ode orun odi eye

kowee, edagirigiri eyele aafin de ode orun odi eye aje, awon mereerin gbera won to gbuede awo ode orun lo, wonni ko gbawon, ki won o to wi tan, orunmila ti de, orunmila ni oun yoo tun won pa leekan si, won wa ni korunmila dakun dabo, orunmila ni ki won o tele oun kalo ode isaluaye ki won o wa lo ba oun tun nkan ti won baje loro oun se, won ba orunmila wa sode isaluaye, won ba orunmila tun gbogbo oun ti won baje loro re se, nje gbogbo nkan ti aje ti baje loro emi L omo L ki won o ba mi tun se lati onilo, won lawon o pada sode orun, orunmila sope won oni pada lo sode orun mo, nitoripe won o ma gbode orun ba oun ni nkan je laye ni, wonni orunmila o, a ko ni gbode orun ba o ni nkan je laye, wonni iwo orunmila jeki a so di oro imule, kafi eku ti kii seku, eye ti kii seye se nkan imule, kafi eja nla eja abori se nkan imule, kafi ewe semolowo semolese se nkan imule, won lenikeni to ba fun awon nn nkan wonyi se imule, awon yoo da owo boo, nje emi L omo L ti fi awon nkan wonyi se imule lati onilo, ki eda owo bomi o, (adua) orangun meji loni koro mi ogun lati onilo ati titi aye mi O daju gidi.

BIBO ASIRI

EWE ori atan nla to ti doti ao ja dada, ao gun mo ose, ao ma fi we.
Ao gbo do korira tia ba wambe

2. Ewe rere ako ati abo, ewe Ola die, ao lo pelu ata ijosi, ao lo po, eyin agric 4, ao fi din eyin na. Ao je ni ihoho.

AWEDANU ATI ASETA

Kororun ki eniyan ni ifokanbale ti idiwo ati ota ba poju fun yan.

Opololo ekolo
Iyo didi kansoso.
Opolo aaye kan
Epo obo die
Ose dudu.
SISE RE:
A o farabale tu iyo yen ao fi se obiripo(CIRCLE) si ileele ao da awon ekolo si aarin re tigbogbo won bati nfi enukan iyo yen dandan niki won ku,ao wa kogbogbo re soju olo aolo kunna pelu epo obo yen aopo ose dudu die mo,ao wa du opolo yen sii aopo ejere mo ose yen. Aopin ose yen si ori kankan(sponge)merindinlogun. Aolo fi gbogbo re we si odo leekanna.

A olo fi iyo didi merindinlogun ati iye ti aba lagbara se saara.
Oniruuru idiwo ni iwe yii maa nmu kuro lara o

ASEJE BASIRI GIDI

Afomo lapa FF,ewe ela topo,a o lopo,pelu iyere a o fise kidirin malu mejeji je lepo niyo,a o ge ikookan si mejo mejo,yio je 16
A o te iyerosun,ni ejiogbe,a o pe ohun si,a o da si obe na,a o he
Oh un....atuyagba kaye loruko tanpe ifa3*
Akikara lanpe iwo esu 3*
Aboloun fankan tipatipa loruko tanpeyin iyami olomo 3*
Eni kilode timon fi igede peyin bayi
Moni oju owo lonponmi
Eni mala malowo
Eni mani owo temi low O
Ela kii gbe ori igi koma LA
Eje kinla,ejeki omo araye wa pe sin mi
Ejeki omo araye wa fi owo owo won sin mi ni
Owo nla nla niki e ma gbewa funmi tori owo nLA ni wonnko le malu
Adura,so je

Ti a ba ri eniti ota ba po fun ju tabi ti awon ota ma nderu ba lori nkankan tabi ti iru enibe ba mo pe ohun ni ota pupo e je ka gbiyanju ise yi wooo

OGUN ISORI

ao pe gbolohun si iyere osun ti a te ni ifa obaraka. Ao wa da sinu eko gbigbona. Ao wa ma fi owo wa mu.

Gbolohun e:

ko sogun mo nile yi(3), Kiki oro loku ti awon awo n da bo ara won, awon ni won pa lobaloba, awon ni won pa loyeloye, owa ku okunrin kan oke ohun ti won fe lo pa. Nibe ni won ti ba obaraka ti n fi owo wa eko gbona mu, won doju ko obaraka, obaraka jo won, won ku iku airoju, won dehin ko obaraka, won ku iku ehinoreyin, won da gbogbo ara ko obaraka, won ku patapata poo. Won ni eleyi ti apa ko ka ka yi ni obaraka. Owo oso, owo aje, owo aye ko ma se ka emi

LOL. Gbogbo eni ba n pe rimi nibi, iku gbigbona ni ki won ko ma ku nitori gbigbona ni eleko n fi owo wa mu. Iba o!

Animals and Their Various Yoruba Names

Cobra	?ka
Ox , Bull	Malu
Spit-Snake	?ebe
Dog	Aja
Hedgehog	?ya
Pangolin	Akika
Crocodile	?oni
Alligator	Ah?nrih?n
Pig	?l?d?
Vulture	Igun, Gunnugun, Gurugu, Akala
Wood-Carrier	Arigi??gi
Hawk	Asa
Palm-Bird	Ologiri
A species of Bird	Olof?r?
Sparrow	Ologo??
Peacock	?kin
Squirrel	?k?r?
Rabbit	Ehoro
crickets	Okinrin
Pouch Rat	Okete
Wild Goat	Edu
A species of Deer	Ekulu
Shark	Akurakuda
Rat/Mouse	Eku/Ekute
Earthworm	Ekolo
Sing Bird	?y?-Orin
Partridge	Aparo
Horse	??in
Donkey	K?t?k?t?
Camel	Rakunmi

Ass	Ibakasi?
Bat	Adan
Pelican	?y?-Ofu
Water-bird	Osin
Dove	Adaba
Viper	Param?l?
Sea-Gulls	P?ju-p?ju
Yellow-haired Monkey	S?mid?l?ti/Oloyo
Sea-Bird	Yanja-yanja
Mosquito	?f?n/Yanmu-yanmu
A species of Beetles	Yanrinbo
Raven	?y?-Iwo
Snail	Igbin/Aginni??
Freshwater Snail	I?awuru
Stay	Igala
Steer	?gb??r?-Ak? Malu
Trout	?ja
Buffalo	?f?n
Monkey	?b? .
Ape	?dun
Lizard	Alangba, -
Lobster	Alakasa
Boa Constrictor	Ere
Boar	?l?d? Igbo,
Gorilla, Baboon	Inaki, Inoki, Iro
Chimpanzee	Elegbede
Phython-Constrictor	Ojola
Electric Fish	Ojiji
Scorpion	Ojogan/Akeekee
Toad	K?nk?
Antelope	Egbin
Tick/Flee	Eegb?n
Hippopotamus	Erinmi

Rhinoceros	?ranko bi Imado.
Reynard (Fox)	K?l?k?l?
Hyena/Wolf	Ikoko
Giraffe	Agbanrere
Cow	Abo-Malu
Crab	Akan
Wild Pigeon	Oriri
Porcupine	Oor?, Eer?, Ojigb?n
Black-Ants	Tanp?p?
Centipede	Tanisanko
Millipede	?kun
Goanna	Awonrinwon
Frog	?p?l?
Chicken	Orom?-Adi?
Nocturnal Animal	Ajao
Hound	Aja-?d? -
Elephant	Erin/Ajanaku
Sheep	Aguntan
Ram	Agbo
Woodcock	Agbe
A species of Woodcock	Aluko
White-feathered Bird	Lekeleke
Chamelon	?ga, Alag?m?
Crane-Bird	Ak? -
Parrot	Odid?r?
Ostrich	Ogongo
White-Ant	Ikan, Ikamudu
Tortoise	Ijapa
Tiger	?kun
Lion	Kiniun
Pigeon	?y?le
Pig/Swine	?l?d?
Eagle	Idi .
Guinea Fowl	Awo

Guinea Fowl	?tu
Guinea Pig	?m?-Ile
Jelly-Fish	?ja-Odo
A species of Bird	Af?r?gbojo/Afe-imojo
Spider	Alantakun
Butterfly	Labalaba
Bee	Oyin
Cockroach	Ayan
Cricket	Ir?
Crab	Akan
Housefly	E?in?in/E?in
Gnats	Kokoro-Oju?ti
Wall-Gecko	?m?nle
Mouse	Eliri
Colt Young Horse	Agodongbo
Woodpecker	Akoko
Palm-Bird	?ga
Insect	Ipin
Red-Ant	Abonilej?p?n
Civet-cat	?ta
Zebra	K?t?k?t?-Abila -
Owl	Owiwi
Lice	Ina-Ori
Bed-bug	Idun
Leopard	Am?t?kun
Hind	Abo-Agb?nrin
Cat	Ologinni
Turkey	Tolotolo
Swallow	Alapand?d?
Kine	Abo-Malu
Stallion	Ak?-??in
Gadfly	Iru, E?in?in- N la
Duck	P?p?y?
Jackal	Akata/Ajako

FREE NOT FOR SALE